# ELETI OFE

'A-NJU-WỌN KO ṢE, WI LOJU'O'

VOL. XIV NO 865 LAGOS SATURDAY APRIL 20— APRIL 26 KOBO MEJI (2D) 1963


NITORI O FE RI JESU:

# Obinrin Kan Sun Si Ite—Oku Lojo Ajinde l'Eko

ITIRẸ (Lẹba Eko)—Obinrin onigbagbọ kan ti orukọ rẹ njẹ Maria Ibukun Ade ti o ngbe adugbo kan ni ibi ti o si jẹ ọkan ninu awọn ariran ọmọ Ijọ Aladura ni a gbọ irohin wipe o sun ninu itẹ-oku (cemetry) ni oru ọjọ Ajinde ti o kọja lọyi pẹlu ireti wipe ati jinde Jesu lọjọ na ni lati ṣe oju on, ki on ba le ri ibukun gba lọdọ awọn Angẹli ninu itẹ na.

Gẹgẹbi alaye irohin na ti a gbọ lọdọ awọn alamulegbe Maria, ni alẹ ọjọ Satide lẹhinti olukuluku awọn ti o nṣọ itẹ l'Eko ti palẹmọ lọ si ile wọn ni o ra pala wọ itẹ lọ ti o si lọ bẹrẹsi ka a-ka-sori kan ninu iwe Psamu (Orin Dafidi) ti ọrọ inu rẹ ba ti awọn oku lọ.

O ṣe eleyi titi di arin-oru ọganjọ ki orun to mu u lọ ni ojiji-o sun orun ọwọ kan lẹhin na ni o taji.

Maria sọ fun alamulegbe rẹ na wipe ala kan ti on la ti on ri awọn aloṣọ funfun kan pẹlu ina abẹla lọwọ wọn ati atẹgun kan ti o nun nini ti on ko ri iru rẹ ri ni o on. Nigbati on taji lojiji on ko le sọ bi aiye ni on wa ji tabi ọrun ni, nigbati o pẹ ọkan on sọji, on tẹ kẹjẹkẹjẹ de idi mọto-bọsi ni Ọbalende.

Gbogbo igbati on la ala na nlọ bi nkan agogo mẹta oru, ṣugbọn nkan bi agogo merin abọ ni on to ri ọkọ wa sile. Nwọn ni rabọrabọ otutu na si wa lara Maria nibiti nwọn gbe ti ngbadura fun un lọwọ nisisiyi.

ỌRỌ OLOTU:

## Inawo Apa Leyi

Awọn Yoruba atijọ ni nwọn ma npa owe wipe "A njẹ ekuru ki o tan ninu awo alakọri kan de o tun gbọn ti ọwọ ri sibẹ. Ọrọ owe wa na le dabi eyiti o fẹ yakọ; Awa Oniwe irohin ELETI-ỌFẸ a ko le ri nkan ti ko ba oju mu ki awọn kan ma ṣe e ki a ma le ṣe ikilọ fun wọn.

Nkan ti o mu ki a pa akọ owe ti o wa loke yi ni irohin kan ti a gbọ ni oru ijeta ninu ile igbimọ awọn aṣofin wa l'Eko wipe awọn fẹ na owo gọbọyi kan lati fi polowo ilu wa ni ọdọ awọn Oyinbo nitoripe nwọn ko ti mọ wa to bi nwọn ti ni lati mọ wa.

Ẹnyin ọkawe wa, ẹ jọwọ ẹ ba wa gbe ọrọ yi yẹwo. O ni iye ọdun ti a fi singba lọdọ awọn Oyinbo Gẹsi ki a to ṣẹṣẹ gba ominira laipe yi. Gbogbo igbati a wa labẹ awọn Ijọba Oyinbo Gẹsi yi ko si ilu kan ti o wa labẹ ọrun ti ko mọ wa rara, a fi ti a ba npurọ tan ara wa jẹ.

(Wo yoku loju ewe keji)

# Oloye S. L. Edu

## NLỌ SI MEKA



Irohin [illegible] gbọ ninu ọsẹ yi ni ti Oloye S. L. Edu, [illegible] Ẹpẹ ti yio wọko ofurufu lọ si Mẹka ati Medina ninu ọsẹ ti mbọ yi.

Eni ọdun [illegible] ni Oloye Edu, o si jẹ ọga alakoso [illegible] ile iṣẹ awọn [illegible] ni ile yi. Ni iwọn ọdun [illegible] Oloye Edu jẹ ọkan ninu awọn ọmọ ilu Ẹpẹ ti [illegible] yan si ile igbimọ aṣofin l'Eko.

Ni ọdun ti o kọja, nigbati agan bẹ silẹ ni Ibadan ti nwọn yan Ijọba pajawiri, Oloye Edu jẹ ọkan ninu awọn adele minisita ti nwọn yan lati ma [illegible] eto iṣẹ Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun lọ.

## ORO OLOTU:-

# Inawo Apa Leyi

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

Ṣe ẹnyin aa mọ wipe olotitọ ilu ni osika ilu? Ti a ba wipe ki a ma ka gbogbo ọna ti awọn Oyinbo ni ilu wọn fi mọ wa iwe irohin yi a kun fọfọ.

Ni ilu awọn Oyinbo Amẹrika nwọn mọ ilu wa lati nkan bi igba ọdun ti nwọn nra awọn ọmọ wa lẹru lọ si Oko-ireke wọn. Lẹhin iyẹn, awọn baba alanu inu wọn da owo jọ lati ran awọn enia wa si ilu wa lati ṣe wasu fun wa wipe IFẸ NI AKOJA OFIN ỌLỌRUN.

Lẹhin eyi nwọn kọ wa bi a ṣe nkawe ati lati ta awọn nkan ọgbin wa bi koko (cocoa), ẹpa, agbọn, ekurẹ, epo pupa ati awọn nkan bẹbẹ.

Gbogbo awọn aṣọ ti awọn baba wa atijọ kọ nlo pẹlu awo-ọbẹ, bata wọn, ẹni ti nwọn fi nsun, ere oriṣa ti nwọn nsin ni nwọn yio so wipe awọn ko mọ ni tabi gbogbo eyiti nwọn ti ko lọ fi ṣe ẹyẹ ninu ile ifihan wọn.

O dabi ẹni wipe awọn Olotu Ijọba Apapọṣe wa na afẹ mu wa ni omugọ nitoripe nwọn ti wa ọkan ninu awọn ti yio polowo ilu wa fun gbogbo aiye na gulẹ si ọdọ wa nisisiyi.

Ọgbẹni Charles Allen ni nwọn pe oruko rẹ, ko si de ile yi rara, Ijọba wa ni nwọn san owo ti o wa na lati ma bi iru wa nidi wa tabi ori ni gbogbo wa fi nrin lọkunrin ati lobinrin.

Inawo apa ni eleyi nitoripe Ọkẹ kan o le ẹgberin pọnun (£25,000) tabi Ọkẹ meji pọnun (£40,000) ti gbogbo ipolowo na a ku si lọdọdun kiṣe ọmọde owo.




## KOKỌRO IGI KOKO

Awọn Oyinbo Ọlọgbin ti tun wa ọna ti kokoro ti o njẹ igi ko ni jẹ nkan ọgbin wọn mọ. Egbogi na lagbara pupọ; aworan yi ni igbati ọkunrin oyinbo kan nlo egbogi na ninu oko wọn. Awọn oyinbo onisowo ti o ṣe egboki jẹjẹrẹ-ti-jẹ-ewe-ata na ni Cooper, Pegler & Co. Ltd. ni Burgess Hill England. Gbogbo rẹ ko ju pọnun mọkanlelogun lọ. O dara pupọ lati pa Kokoro ti o njẹ Koko tabi igi Koko (Cocos).



# AKIYESI

**E ka Iwe Eleti-Ofe ni ose ti mbo ti o kun fun irohin aladun ati nipa bi nwon ti sin oku Ologbe Abibu Oluwa, oni-mo-lo si ati irohin awon Alhaji ati Alhaja ni ilu Jeda**

# Itan Awon Omo (Yoruba) Oduduwa (2)

### Iwe Alufa Atilade

Lati pada si Ile-Ifẹ di ọran itiju fun Ọranyan. Nigbati ko mọ eyiti on yio ṣe mọ, o pinnu lati tẹ ilu titun miran do. O ranṣẹ si Ọba Ibariba, leti ilẹ ẹniti o do si pe nibo ni o yẹ ki on fi ṣe ibugbe. Imọran Ọba Ibariba ni o mu ki Ọranyan lọ si ẹsẹ oke kan ti a npe ni Ajaka nibiti o gbe tẹ ilu Ọyọ do. Eyi yi ni ilu Ọyọ ti igba lailai ti a npe ni Ọyọ Ajaka tabi Ọyọ Ile.

## LATI OWO AKOWE

Nigbati Ọranyan ko pada wa si Ile-Ifẹ mọ, o ranṣẹ lati bere ohunkohun ti ti o ba fẹ ninu ohun ini ti baba wọn lọwọ Adimu, ẹniti o fi de ile bi babalorișa ni afin Babalorișa yi di ọlọrọ, o si di alagbara gẹgẹbi eniti o ni lati ma sure fun gbogbo ọba tio ba jẹ ni Ilẹ Yoruba. Titi o fi di ọdun 1810 (A.D.) nigbatl Ọba Abiọdun ku gbogbo Ilẹ Yoruba wa ni alafia ati irọra.

Lẹhin iku Ọba Abiọdun ni Afọnja ti Ilọrin ẹniti iṣe Arẹ-ọna-kakanfo fun awọn Yoruba bẹ awọn Fulani ati Hausa lọwẹ lati ditẹ si Alafin Ọyọ. Lẹhin igbati nwọn ti ran a lọwọ ninu ọtẹ yi tan, nwọn yiju pada si on na, nwọn si gba ilu Ilọrin lọwọ rẹ. Nigbati awọn Fulani ti fi idi mulẹ dada ni Ilọrin, nwọn wa do ti ilu Ọyọ Ile, nwọn si ko o.

Lati Ọyọ Ile ni Ọja ti wa tẹ Agọ do, eyiti o di ilu Ọyọ ti ode oni. Gẹgẹbi aṣa ataiyebaiye ti ilẹ Yoruba, ọba jẹ baba fun gbogbo awọn enia ti o ba njọba le lori, awọn enia na si jẹ ọmọ fun u; nitori eyi, a le pe gbogbo awọn enia ti awọn ọmọ Oduduwa ba njọba le lori pẹlu ni ọmọ Oduduwa.

### Awolowo Ni :-

## ON KO LE BA SARDAUNA SE IJOBA PO

EKO—Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, baba egbẹ Afẹnifẹre (AG.) ti awọn ọlọpa mba ṣe ẹjọ wipe awọn ditẹ si Ijọba Apapọṣe pẹlu awọn ọmọlẹgbẹ rẹ ni on ko le ba Ọlọla Alhaji Amodu Bello, Olotu Ijọba Ipinlẹ Ariwa, pẹlu Ọlọla Alhaji Tafawa Balewa tiṣe alakoso Ijọba Apapọṣe se ijọba pọ nitori ọna ti ko ba oju mu ni nwọn ngba ṣe ijọba ti nwọn.

Eyi ni idahun ti Oloye Awolọwọ da Ọgbẹni Basil Adedipẹ tiṣe agbẹjọro Ọba lohun ibere ti o mbii nigbati o nro ẹjọ a-wi-jare tirẹ ninu ọsẹ yi.

Oloye Awolọwọ ni Ọlọla Sardauna ni ẹniti o fẹ lati ma ni gbogbo awọn ọmọ ilẹ Nigeria lara, o ni pẹlu iwa tani le n u mi ni Sardauna fi njọba le awọn ara ilu rẹ lori ni Oke Ọya.

Oloye Awolọwọ ni ti o ba je wipe on ni on wa ipo alakoso ti Ọlọla Alahaji Tafawa Balewa wa ni, ni on yio sa agbara lati ri wipe irẹpọ wa larin awọn Ijọba Ipinlẹ iyoku.

O ni gẹgẹbi Olori alatako, iṣẹ ti on n lati ri wipe on tọ awọn alakoso Ijọbọ si ọna ti o to. Oloye Awolọwọ ṣe alaye siwaju wipe ti awọn alatako ba dapọ lati ba awọn Olotu Ijọba Apapọṣe ṣe ijọba gbogbogboo ko ni si onibawi mọ fun awọn ti nṣe akoso Ijọba, nkan ti o ba si wu wọn ni nwọn yio ma a ṣe fun awọn ara ilu.

Oloye Awolọwọ ni lọjọ ti ija bẹ silẹ larin ile Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun, on ni on so fun Alhaji Tafawa Balewa ninu ẹrọ fonu (telephone).


JAPANESE BICYCLES



• STRONG
• SPEEDY
• SMART

TODAY
JAPANESE BICYCLES COVER
THE WHOLE WORLD

For import informations apply to:
JAPAN BICYCLE
TRADE CENTER
P. O. Box 4117, BEIRUT LEBANON
CABLE EXBIKE BEIRUT

# ELETI—OFE

A NJUWKO ŞE WI LẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS 28, Kosọkọ Street, Lagos. P. O. Box 467
CABLE & TELEGRAM "ELETI-ỌFẸ" LAGOS Phone 23370
VOL XIV. NO 865 SATURDAY APRIL 20 APRIL 26 1963


# Abibu Oluwa D'ologbe

Bi ere, bi awada ni a gbọ iku Abibu Ọlatunji Oluwa, ẹniti gbogbo enia ni igun mẹrẹrin Nigeria mọ fun gbogbo orin sakara ti o kọ fun faaji awọn enia wa lọkunrin ati lobinrin nilẹ yi ati oke okun.

Ọkan ninu awọn ọmọ oloye Oluwa ni Ologbe na je ni ilu Eko; ẹni ọdun mẹrindinlogọta ọdun ni o si kọ orişirişi orin faaj nigba aiye rẹ ti o fi ki awọn enia pataki-pataki ninu awọn ọba ati awọn ijoye ilẹ wa.

## Iku Mu Olohun Iyo Lo

Ologbe Abibu kişe oni-sakara ti ba ni ja ni ibi ere şişe, ko ni ọta pẹlu ẹrin ati ayaya ni o fi nşe ere tirẹ ni nibikibi ti nwọn bu pe e si.

Gẹgẹbi ọrọ on na ninu orin kan ti o kọ laipe yi, o ni "iku pa lagbaja, iku lakaşegbe, GBOGBO WA LA O KU". Adura wa ni pe ki Ọlọrun ki o fi iku rere pa ni, şugbọn ẹniti o ba fẹ ku iku rere ọwọ ara rẹ ni yio fi fa a.

Ọlọrun ti fi iku rere pa Abibu Olohun iyọ. Abibu lo lọ ohun rẹ ko lọ. A mọ wipe loni gbogbo ile ti nwọn ba nfi awo rẹkọdu sakara şe faaji ni nwọn yio mọ niran Ologbe na.

Abibu Oluwa, Ọrun re !

---

## Mo Gba Fun Adajo Onyeama

Olotu, mo gba fun adajọ-kotu nla ti nwọn npe orukọ rẹ ni Daddy Onyeama, t'i awọn kan fẹ se ọrọ mọ lẹnu nipa ọrọ ẹkọ kan ti o ba awọn ọmọ ilewe ti nwọn npe ni King's College sọ wipe o yẹ ki awọn oşelu wa ma gba itumọ ti ti awọn adajọ ba sọ lori awọn ofin ilu wa.

Ọrọ ti adajọ yi sọ ko pọju ẹnu rẹ lọ rara nitoripe bi awọn alakoso Ijọba wa ba nfẹ alafia ninu ilu, o yẹ ki nwọn ma teti silẹ lati ma gbọ nkan ti awọn ara ilu ba nro nipa bi wọn ti nşe ilu si nigbagbogbo. Enia kan ko nje awa de.

Ijọba kijọba ti o ba wa ti ko fẹ gba ọrọ ibawi awọn ara ilu yio şina, nitorina ẹ ma fi ọwọ bo wa lẹnu rara mọ o.

Emi ni,

F. Atunrabi

Abule Ijẹşa,

Yaba

# Iwe Si Olotu

## Imale Ba Awon Alhaji Soro Nipa Fila Won

Inu mi yio duu ti ba gba mi laye lati dasi ọrọ awọn Alhaji ti nwon in ki akowe ẹgbẹ wọn Zumuratul-Hiyaji lọ fi ọ r ọ awọn ti o mba awọn lo fila, aşọ ẹwu pọ san Ijọba.

Ẹ jọwọ Olotu, ẹ ba wa gbe ọrọ na yẹwo, emi ko ri ewọ ninu a nlo fila alapẹrẹ ati ẹwu gẹrẹjẹ ti awọn Alhaji nwọnyi n l o rara; imura ẹşọ ni fun enikẹni ti o ba ti ni owo rẹ.

Ẹ jọwọ ẹnyin Alhaji wa ẹ jẹ ki onipes ki o şe yin. Ọpọlọpọ awọn ọmọ Musulumi ni a nri ti nwọn nda aşọ bi oniwasu Kiriyo, ti nwọn si nloo, ko si ẹniti o mu nwọn lọ fi s u n lọdọ Ijọba.

Bi enia ko ba lọ si Mẹka ti o ba nde fila alapẹrẹ ko ni ko di Alhaji, bi Alhaji ko ba si de fila na ko ko ni ki o pe awọn obinrin ki nwọn ma da lohun ti o ba ti ni owo lọwọ, nitoripe mo gbọ wipe nitori awọn obinrin ni nwọn şe ẹsS yi.

Awọn obinrin ko bikita bi ọkunrin oni fila Alhaji yio tọju wọn, bi ko ni tọju wọn ko sa ti jẹ Alhaji ni nwọn fẹ, ọkọ tọju t i ya niyẹn.

Mo dupẹ aye ti ẹgba mi.

Ita Alagba,    Emi ni,

Eko.    Tawakalitu




**PLANNING NOW**

means a

**SUCCESSFUL FUTURE ...**

Planes are made for buildings for strength and security.... you, too, must make plans. Ensure the security of your future and that of your children by starting a programme of Life Insurance NOW with:

**Great Nigeria Insurance Company Limited**

**(Incorporated in Nigeria)**

HEAD OFFICE: 39/41 Martins Street, Lagos, P. O. Box 2314 Tel. 25251.
Branches:- Abeokuta, Agege, Akure, Benin-City, Ibadan, Ijebu-Ode, Ilesha, Oshogbo, Sapele and Warri.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## (Lati Owo Ayiluka)

### Owo Ni Koko

Mo ki ẹnyin ọkawe mi pe ẹ ku wahala ọdun Aiinde ti a ṣe kọja yi, gbogbo wa ıọmọde lagba pẹlu awọn Onigbagbọ ati Imale ti a ṣe wahala oriṣiriṣi alejo ti nwọn wa ki wa ni Abẹokuta, Ibadan ati Ijẹbu.

Mo gbọ wipe gbogbo awọn ijoye ati nwọn Ọba Ipinlẹ Iwọ-orun ti o wa si ile igbimọ awọn ọba ni nwọn rẹrin pada si ile wọn nigbati awọn alakoso Ijọba ipinlẹ na fọwọ sọ aya wipe awọn yio san owo atẹhinwa ti rogbodiyan ko jẹ ki awọn roju san fun wọn.

Mo gbọ wipe ọpọlọpọ ninu wọn ti nwọn ti wa moto ayọkẹlẹ wọn joko sile nitori owo epo moto (petrol) ti ko si ni nwọn ti tun pe awọn dẹrẹba wọn pada nitoripe owo ti de; awọn obinrin ti nwọn ti binu pada lọ si ile wọn ti tun npada wa si agbala awọn ijoye Ọba. Ṣe ẹnyin na wa ri wipe owo ni keko.

Anu ṣe mi lati tu'fọ Ogbẹni wa Abibu Ọlatunji Oluwa, ẹni pataki ninu awọn Olorin Sakara l'Eko ti awọn ọmọ igbayi npe ni BABA NI FEDERAL.

Emi ko ni sọ ọrọ pupọ lọsẹ yi nipa Ologbe na nitoripe mo gbọ wipe Olotu Eleti-Ofe ti sọ pato nipa baba ti o kọrin fun alejo ti o kọrin fun onile.

Mo gbọ wipe lẹhin igbati awọn Musulumi ba ṣe oku ti nwọn tan awọn sanmọri Idumọta, Olowogbowo, Isalẹ-Eko ati awọn ọpọlọpọ enia lati Ibadan, pẹlu awọn Kelani oni Sakara, Aka pẹlu Ojindo lati Abẹokuta mbọ wa ṣe ere nibi oku Abibu na; gbogbo rẹ ni yio ṣe oju mi Ayiluka ni Idumọta.

### Ero Meka

Mo gbọ wipe ọrẹ mi Oloye S. L. Edu, 'baba-Ibiye' ninu Ijọba pajawiri ni Ibadan ti ọjọ ana nmura lati lọ si ilu Mẹka ati Mẹdina lati ṣe ẹsin. Ọlọrun ko pa alọ ati abọ mọ o.

Ṣugbọn bi ẹ ba de emi Ayiluka na a wa pade yin a si ma kọ orin "Oke Arafa to gun ba rika e"






150 Li


175 Tv

GET AROUND BETTER-TRAVEL

Lambretta

2nd SERIES 150 Li ........ £145
'SLIMSTYLE' 150 Li ........ £162
'SLIMSTYLE' 175 Tv ........ £175

LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS (18) • IBADAN • KANO • KADUNA • JOS • PORT HARCOURT • ABA


# Ikilo Ko Si

Olotu kinni o ṣe ti o jẹ wipe ọpọlọpọ awọn obi ko le ma ṣe ikilọ fun awọn ọmọ wọn ti nwọn ma nlọ luwẹ ni odo okun lọdọdun lọjọ Ajinde.

Ti awọn ọmọkẹkẹ na ba ti de eti Okun nṣe ni nwọn ma nsa lọ awọn ti nwọn ba ma wọn lọ lọwọ ki nwọn ba le ri aye ṣe ere buruku ti wọn fẹ ṣe.

Ninu ajọyọ Ọdun Ajinda ti o lọ yi, a gbọ wipe o to awọn mejila ti awọn obi wọn nwakiri l'okun. Ẹnyin obi ẹ ṣe ikilọ fun awọn ọmọ yin.

Emi ni,

Ayindo

Ibadan St.,

Ebute-Metta.

# Awon Ole Da Onimoto Lona Lona Aba

ABA—Awọn ọlọsa kan da awọn oni mọto akẹro lọna lọna Aba ni ọsẹ ti o kọja yi nwọn si ko gbogbo ẹru ti o wa ninu awọn mọto na.

Irohin ti a gbọ nipa awọn adana na ni wipe ọjọ ti nwọn lọ piyẹ yi oju ọna Asaba si Bini ni nwọn lọ gbe mọto wọn si, mọto na tobi, nwọn si fi da ọna meji, awọn ọlọsa na si fi nkan bo oju bi gareta, nwọn wa nda awọn onimọto ti o ba ti fẹ kọja duro.

Gbogbo ẹru ti nwọn ni ko lọdọ awọn ero ... ota na nlọ si ọkẹ kan-o-le-egbẹ-ogbọn ... (£25,000); awọn ero na ja finfita diẹ pẹlu awọn Ọlọsa na ki nwọn to ko ẹru wọn na lọ.

Nwọn ti ko awọn ti o fi ara pa lọ si ile awọn alaisan ni Onitsha.

# Eleti—Ofe Daraba

## ONIBOLU DORIKODO



Aworan ti e nwo yi ni igbati Ogbeni Bill Brown, baba asole bolu fun awon Tottenham ni ilu Oyinbo gbe okiti nigbati o fe mu bolu ti awon omo egbe agba-bolu ti nwon npe ni West Bromwich fe gba wole laipe yi. Sibesibe awon omo egbe Tottenham ni nwon pa won layo na.



**AKIYESI**

E ka oro **Ayiluka Eleti-Ofe** loju ewe karun. O kun fun Irohin **Asiko.**

# Ijo Aladun

Aworan yi ni igbati Olola Bale ilu Kenti (Duke) ati iyare lo si ilu oke Uganda ni Afirika ti awon ara ilu na beresi lu ilu, ti nwon si njo ijo aladun fun won. Ogbeni Milton Obote tise Olotu ilu Uganda ni o wa ni apa osi aworan yi nibiti o gbe ti mba awon olola bale Kent na ati iyawo re soro.

# BBC In Religious Broadcasting

## (By A Special Correspondent)

"Here we are passing through a time of tension and crises, and I find that your early morning brief Daily Service gives strength and courage to face whatever each day may bring forth. Thank you for it." this thank-you came to the BBC from a listerner in Katanga at the time of some of the worst troubles in the Congo. By contrast, not long ago telephones were ringing at the BBC Television Centre in London with complaints from viewers who though the BBC has gone 'too far' in devoting the television Sunday evening religious programme to a popular musical version of the parable of The Prodical Sons; a broadcast which was praised by others. Instances like these illustrate the wide range of BBC religious Broadcasting, and two of its basic aims: to support and strengthen the faith of those commited to the life and work of the Christian Churches and enable them to join in worship when prevented from personal attendence through distance sickness old age or other reasons; and secondly, to reach out to those on the fringe of the life of the churches or quite ouside it. Among the latter may young people be reached through out presentations of the christian story in modern rather than traditional terms. Many people of all ages are led to think mor deeply about there faith—or lack of it through the talks and discussions which are a regular and Important part of BBC religious broadcasting, bouth in sound radio and television.

Many religious broadcast are concerned with showing what is most is significant in the relationship between the Christian faith and the modern world, and how the churches are tackling the task and opportunities of today. A recent example was The Church and the World series broadcast in the BBC General Overseas Service. Religious broadcasts in the BBC General Overseas Service have a specially valusble task in linking Christians round the world with churches in Britain and keeping them.

Religious broadcasting is now so widely accepted that it is hard to realised that when the BBC came into being in November 1922, grave doubts were expressed, both in the Church and the BBC, as to the propriety of broadcasting acts of worship. Some felt that it would be irreverent to broadcast a Service or a prayer, while other were afraid of causing disputes between the Christain chuches. It was the BBC's first Director General, now Lord Reith, who took the initiative in securing a fundamental place in Bristish Broadcasting for the Chritian religion. The first religious address was broadcast on Christmas eve 1922 and from January 21, 1923 a religious programme was broadcast from the studio every Sunday evening. Mr. Reith, as he then was, approached the Archbishop of Canterbury for advice in selecting suitable speakers. The Archbishop called a meeting of leaders of the main Christian churches in Bristish and it was at this meeting.

# New Sierra Leone Stamps Printed in England




Collectors all over the world has welcome this colourful new series of Sierra Leone stamps showing many of the flowers to the found in the country.

These Stamps have been printed in multicolour photogravure on Sierra-Leone watermarked paper by Harrison and Sons Ltd., of London. Each measures 39mm x 29mm from perforation.

Sierra Leone's many matural attractions, including hills and fine beaches, play an important part the country's expanding tourist industry which will soon become important in the economy of the country — an independent member of Commonwealth since April 1961.

## Adajo Ni Ki Nwon Pa Awon Olote Ghana

ACCRA—Adajo kotu nla kan ti Ijoba Dokita Nkrumah da sile lori oro olote ilu ni ki nwon lo yegi fun awon enia marun ti nwon dite ianti fi bombu oloro pa Olotu-na.

Nigbati nwon nro ejo olote na awon adajo agba meta ni o wa lori aga igbeje, oruko awon adajo na ni Oloye Arku Korsah ti se olori awon adajo, Ogbeni W. B Van Lare ati Sarkodee Addo. Awon adajo na ni awon gbagbo wipe nitoto ni awon enia na dite si awon alakoso ilu.

Nigbati nwon nro ejo okan ninu odaran na wipe n toto ni awon se ipade kan lona oko kan lati ju bombu sile Dokita Nkrumah ki o ba joqo nu fun awon nitoripe ona ti o fi nse Ijoba na ko wo rara fun awon. Osu kan ni nwon fi ro ejo na.

Okan ninu awon arufin na ni omo ilu Nigeria ni on sugbon nwon ko gba fun un. Oruko awon enia marun ti nwon ni ki nwon yegi fun na ni Teiko Tagoe, eni ogun odun; Joseph Mensah eni odun metadinlogota; Adotie Addo, eni odun merinlelogbon; Malam Mama Tula; ti o ni omo ilu Nigeria ni on ati Anum Yemoh.

Nwon ni 'ko si aforiji lodo adajo kan mo a fi ti Dokita Nkrumah papa ba wipe on darijin won.

IGI DA!

### ABIBU OLUWA D'OLOGBE
### Olohun Iyo Rorun Alakeji



EKO— Igida ! A gbo ju igba nu ni ti irohin iku Ogbeni Abibu Oluwa, Olori awon Olorin ilu Eko. Ni kutukutu owuro ijerin (Tuesday) ni irohin na ta si, awa Eleti-Ofe leti, awada ni a ko pe oro na sugbon nigbati a de ile re ni Idumota nse ni a ba awon omo ati ebi re ti nwon dori kodo.

Eni odun merindinlogota ni Ologbe na, o si fi omo mewa lokunrin ati lobinrin sile. Abibu ku sugbon o fi ohun sile. Ninu awon enia ti o fi orin re ki ti awon na si ti jade laiye ni awon bi Eshugbayi Eleko Oba Ladapo Ademola, Alafin Oyo, Adamo Akeju Oba Onikoro, Sanni Adewale, Buramo Igbo, Buramo Ekun, Tiamiu Savage, Tukuru Ajibabi,

Adebisi (Ibadan) Folawiyo, Sehinde Oshodi, Dokita Vaughan, Josah Doherty, Herbert Macaulay, Olatunji Fowler (baba Ibadan) Kasi-Karamo Aruwe (Cafo) Rufai Apatira Wahabi Grillo Amusa Ajibike ati Yekinni Ajadi.

## Nwon Fi Ile Mosalasi Tuntun Le'le Ni Oko-Baba

EBUTE—METTA — Awon enia pataki pataki ni nwon wa si ibi aseye ile Mosalasi tuntun kan ti nwon so oruko re ni iranti Ologbe Ibikunle Ojikutu (baba Alhaji A. A. Ojikutu) ti nwon fi le'le ni ojo Ose ijeje ni Osholake ni Oko-Baba.



**Alhaji Musa Ya-Adua**

Alaga ojo na, Ogbeni S. B. Igbinso bi awon ti fi igi pako ko mosalasi ti awon ko ko sibe lati nkan bi odun medogbon ati bi Lemomu awon Alufa Tijani Muritala ti se wahala titi larin awon aborisa Oko—Baba pe ki nwon le di Imale.

Alaga na ni were ti awon ti lo kigbe ba Alhaji Ojikutu wipe awon nlo iranlowo lodo re ni o ti fun awon ni ile kan pelu owo goboyi lati fi ko mosalasi tuntun na.

O ni awon si tun dupe pupo lowo Minisita alamojuto eto arin ilu Eko, Alhaji Musa Ya-Adua ti o se gudugudu meje fun awon Alhaji Ojikutu so fun un wipe awon nfe ki Ijoba ran awon lowo nipa Mosalasi tuntun na ti awon fe ko.

## Alhaji Ti Ko Yan Saaka Ju Iwe Nu

EKO—Okunrin ti o fe ba awon Alhaji tuntun ti nwon nlo si Meka woko ofurufu ni ijeta ni Ikeja ni a gbo wipe o ju iwe oko ofurufu re nu ati iwe ase lati fi ilu sile (passport.) Gbogbo awon ti nwon ri bi o ti ndamu sihin sohun ni nwon ba kedun.

Awon kan ti nwon mo Ogbeni daradara ni o je enikan ti o hawo pupo, nwon ni boya ko yan saka to ke to dide nile ni iru idamu fi baa. Ju gbogbo re lo, o ti ko eru re pada si ibiti o gbe de si l'Eko, awon to ko ni awon yio ba se paramu lati ba wa iwe re na.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Lagos, Box 467 Phone 23370 Editor (Olotu) Ola Onatade, 15, Kosoko Street, Lagos.